Bibeli fun awon omode

# Awon Ise Iyanu Jesu



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: E. Frischbutter; Sarah S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Jesu se opo ise Iyanu. Ise iyanu je ami lati fi Jesu han gegebi omo Olorun nitooto. Ise iyanu akoko sele nibi ase igbeyawo. Isoro de. Waini to wa ko lee to fun gbogbo eniyan.



Maria, iya Jesu, so fun nipa isoro naa, o si so fun awon iranse pe ki won se ohun gbogbo ti Jesu ba pase.



Jesu wi fun won pe, “E pon omi kun ikoko wonyii.” O tile se e se ki awon iranse naa beere pe “omi, abi ki lo pe e?” Beeni, omi ni Jesu beere.



Jesu wa so fun okan lara awon iransenaa pe ki o bu ninu ikoko nla ki o sigbe e to alakoso ase naa lo lati to o wo. Omi yii ti di waini! Waini ti o dara! Waini ti o dara julo!



Enu ya awon iranse naa.
Jesu so omi di waini.
Olorun nikan ni o le se
iru ise iyanu yii.



Jesu se awon ise iyanu miiran. Ni asale ojo kan, oun pelu awon omo eyin re lo si ile Peteru. Iya aya Peteru nse aisan iba gidigidi.



Jesu fi owo kan owo obinrin naa.  Ni iseju aya, ara re da.  O dide lati salejo Jesu ati awon omoeyin.



O dabi pe gbogbo ilu pejo ni enu ona li asaale. Awon alaisan wa, afoju, aditi, odi, aro, Koda, awon ti o ni emi esu ninu won wa pejo sodo Jesu. Nje o le ran awon opolopo eniyan yi lowo?



Jesu, omo Olorun, le se iranlowo. Lotito, O ran won lowo. Gbogbo awon ti o to O wa ni o wosan. Awon ti won nfi opa rin tele si di eni ti o n fo fayo, ti won si nrin.



Awon miiran wa, ti
arun ete ti ba awo
ara won je pupo.



A mu won larada, a
so won di mimo bi
Jesu ti wo won san.



Awon okunrin ati obinirin tiemi esu n yo lenu duro niwaju Jesu. O pase ki emi esu naa jade. Bi awonemi esu naa tin jade, awon eni ti won kun fun eru ati ibanuje di eni ti ara won bale ti won si kun fun ayo.



Leyin agbo, awon okunrin merin kan n gbiyanju lati je ki ore won ri Jesu. Sugbon won ko le sunmo ibi ti O wa. Kinni won le se?



Won gbe alaisan naa gun ori orule, awon ore yii ya orule won si so ore won kale. Nisinyii, oti sunmo Jesu.



Jesu ri ipe awon ore merin yii ni igbagbo. O wi fun alaisan naa pe, "A dari ese re jin o. Gbe akete re, ki o si rin" Okunrin naa dide, ara re si ya. Jesu ti wo o san.



Leyin eyi, Jesu wa ninu oko oju omi pelu awon omo eyin re. Iji to bani leru dide loju agbami. Jesu ti sun. Awon omo eyin ti eru n ba lo ji I. Won wipe, “Oluwa gba wa, awa gbe!”



Jesu pase fun iji naa, “Dake je.” Logan riru okun duro. Awon omo-eyin bere sii bi ara won leere pe, “Iru okunrin wo ni eyi? Okun ati iji n gbo tire.” Won gbagbo pe Jesu je omo Olorun nitori ise iyanu re fi ogo re han. Awon omo eyin ko mo eyi, sugbon won yoo ri ti Jesu yoo maa se awon



ise iyanu nla biO se nsin Olorun laarin awon eniyan.

# Awon Ise Iyanu Jesu

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Matiu ori kejo ati Ikesan,
Maaku ori kinni ati ikeji, Maaku ori kerin,
Luku ori kejo, Johannu ori keji

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.